# REBEKA, APẸẸRẸ IYAWO KRISTI

**Gẹnẹsisi 24:34-67**

**ẸKỌ 13 --- FUN AGBA**

**AKỌSORI: "Ẹ jẹ ki a yọ̀, ki inu wa ki o si dùn gidigidi, ki a si fi ogo fun u: nitoripe igbeyawo Ọdọ-Agutan de, aya rẹ̀ si ti mura tan" (Ifihan 19:7).**

**I Iranṣẹ Abrahamu Jiṣẹ ti A Rán an**

1 O sọ̀rọ nipa Isaaki, ọmọ Abrahamu, ati ogun rẹ̀ ti a ti ṣeleri fun un, Gẹnẹsisi 24:34-36; 13:14, 15

2 A ti fun Elieseri ni ojuṣe lati wá aya ti o tọna fun Isaaki, Gẹnẹsisi 24:37-41

3 A dán ẹni ti yoo jẹ́ iyawo naa wò ni ibi kanga, idahun rẹ̀ si yọri si rere, Gẹnẹsisi 24:42-46; Romu 12:1

4 A ṣe ẹni ti yoo jẹ́ iyawo yii lọṣọ, Gẹnẹsisi 24:47, 48

**II Ipè ti A Dahun**

1 Elieseri sọ̀rọ nipa ominira olukuluku lati dá yàn, Gẹnẹsisi 24:49; Ifihan 22:17

2 A fun Rebeka ni anfaani lati yàn, Gẹnẹsisi 24:50-58; Isaiah 1:19

3 A ta ẹbi naa ni ọrẹ pupọ, Gẹnẹsisi 24:53

4 Rebeka gba ire idágbere, o si rin irin-ajo lọ si ile rẹ̀ titun, Gẹnẹsisi 24:59-61

**III Ipade Isaaki ati Rebeka**

1 Isaaki duro de iyawo rẹ ni aṣaalẹ nigba ti o jade lọ ṣe aṣàrò ni papa-oko, Gẹnẹsisi 24:62, 63; Sekariah 14:7; Matteu 25:10

2 Rebeka mura silẹ lati pade ọkọ rẹ̀, Gẹnẹsisi 24:64, 65; Ifihan 19:7

3 Ipade naa ṣẹlẹ, Gẹnẹsisi 24:66, 67; 1 Tẹssalonika 4:16-18; Matteu 24:26-28

## ALAYE

**Ogún Wa ninu Kristi**

"OLUWA si ti bukún fun oluwa mi gidigidi; o si di pupọ̀: o si fun u li agutan, ati malu, ati fadaka, ati wurà, ati iranṣẹkunrin ati iranṣẹbirin, ati ibakasiẹ, ati kẹtẹkẹtẹ." Abrahamu jẹ́ eniyan nlá, o si n ṣe akoso ọpọlọpọ ọgọrọọrun awọn iranṣẹ, ṣugbọn ajogun kán ṣoṣo peré ni o ni, Isaaki. Irú ọlá wo ni a o fun ẹni naa ti yoo fẹ ẹ, ti yoo si di ajumọ-jogun pẹlu ohun gbogbo ti o ni!

Bi o tilẹ jẹ pe Abrahamu jẹ ẹni ti o ni ileri ayeraye, sibẹ fadaka ati wurà, agutan ati maluu rẹ̀ jẹ́ ohun igba diẹ, kò si ni pẹ́ fi wọn silẹ̀. Bi o ti wu ki o ri, a kò le fi ọrọ̀ ati ọlá ti a fun iyawo ọmọ rẹ̀ yii wé ọlá ti a o fun gbogbo awọn ti yoo dé ojú ọwẹn lati jẹ́ Iyawo Kristi lọfẹ̀ẹ́. Rónu le ogo ti a o fi hàn nigba ti a o fi awọn ọmọ Ọlọrun hàn, ti a o si kede wọn bi "ajogun Ọlọrun, ati ajumọ-jogun pẹlu Kristi" (Romu 8:17). Gbogbo ẹdá ni o n rọbi ninu irora ati aibalẹ̀-àyà, ti wọn si n duro de akoko naa nigba ti a o fi Iyawo Kristi hàn.

**"Pipe Ẹwa"**

Johannu ayanfẹ kofiri ẹwà ti a ko le juwe nigba ti a fi "iyawo, aya Ọdọ-Agutan" hàn án (Ifihan 21:9). Anfaani yii lati jẹ́ Iyawo ati ajogun ni a ṣi silẹ fun gbogbo Ijọ Ọlọrun ti a ti rà pada! Njẹ o ha le fi ainaani kọ̀ ipe Ẹmi naa – ti n pe ọ lati jẹ́ Iyawo Kristi?

**Dide Oju-Ọwẹn**

"O si yara, o si sọ ladugbo rẹ̀ kalẹ kuro li ejika rẹ̀, o si wipe, Mu, emi o si fi fun awọn ibakasiẹ rẹ mu pẹlu." Ṣiṣe ohun ti o kere, ṣugbọn o fi ipò ọkàn ti o ṣọwọn nigba pupọ hàn -- ifẹ lati ṣe awọn ohun ti a fun ni lati ṣe: ati ju bẹẹ lọ, lati ṣiṣẹ isin wa ju bi ojuṣe wa ti beere lọ, isin atinuwa.

"Emi o pọn fun awọn ibakasiẹ rẹ pẹlu." Igba mẹrin ti ọ̀rọ yii tabi ohun ti o jọ ọ, fara hàn ninu ori iwe yii fi dandan ti Ọlọrun fi lé lilọ si "ibusọ keji" hàn. Awọn eniyan wọnni ti wọn n tàn jade ninu oju-iwe Ọrọ Mimọ́ Ọlọrun ni awọn ti wọn ṣe ifararubọ ti wọn si ṣe awọn ohun iyanu nlá jù eyi ti a béèrè lọwọ wọn.

**Ẹbun lati Oke Ọrun**

Nigba ti Ẹmi Ọlọrun ba ri irú ọkàn bẹẹ, bawo ni O ti ni ifẹ tó lati fi awọn oore-ọfẹ Ọ̀run ṣe e lọṣọ, eyi ti a fi ọṣọ jufù ati oruka éti ti Elieseri fun Rebeka ṣe apẹẹrẹ. Awọn oore-ọfẹ Ẹmi ti n sẹ̀ gẹgẹ bi iri Ọrun ni ọ̀ṣọ́ Iyawo Kristi. Awọn ni ọ̀ṣọ́ ailediyele ti Ọlọrun n fun ni; kò si ohun ti o n ṣe ọkàn lọṣọ bẹẹ gẹgẹ bi Ẹmi Ọlọrun. Irisi oju paapaa fi ogo ti o n wá si ọkàn ẹni ti a gbala hàn, ti a sọ di mimọ́, ti o si tẹ̀ siwaju titi Ọlọrun fi tú Arọkuro Ojo sinu ọkàn rẹ̀.

Ẹgbọn Rebeka ọkunrin ti le ri i pe aburo oun ti pade ohun kan ti o ti yi ayé rẹ̀ pada. O ri ọ̀ṣọ naa, o si ni ifẹ si eniyan Ọlọrun yii. Ayé yii kò le ṣe ki o má ṣe akiyesi, yoo si bèerè ohun ti o mú ki ọmọ Ọlọrun maa ràn pẹlu ogo Rẹ bẹẹ.

**Ẹ jẹ ki A Yara Kankan**

"Nwọn si dide li owurọ̀, o si wipe, Ẹ rán mi lọ si ọdọ oluwa mi. Arakunrin ati iya rẹ̀ si wipe, Jẹ ki ọmọdan na ki o ba wa joko ni ijọ́ melokan, bi ijọ́ mẹwa, lẹhin eyini ni ki o ma wa lọ." Labani gbà pe nnkan yii wá lati ọdọ Ọlọrun ati pe oun kò le sọ buburu tabi rere nipa rẹ̀, ṣugbọn o kan gbiyanju lati mu un falẹ diẹ. Nigbakuugba ni o n ṣẹlẹ bẹẹ ti awọn eniyan n gbà pe Ihinrere ti Ọlọrun ni tabi pe awọn nnkan kan ni ohun ti wọn gbọdọ ṣe, ṣugbọn wọn n fẹ fi falẹ diẹ. Eyi jẹ́ ọ̀kan ninu awọn ọgbọ́n ẹ̀wẹ́ ẹ̀ṣu nigba ti o ba ri i pe oun ko le mú ki eniyan sẹ́ iṣẹ Ọlọrun: yoo saa mu wọn ṣe alainaani, yoo si maa mu wọn ṣe alainaani siwaju si i. "Awa o ti ṣe là a, bi awa kò ba nani irú igbala nla bi eyi?" (Heberu 2:3).

"Ẹ máṣe da mi duro" ni ipè Ẹmi fun gbogbo awọn ti yoo maa ṣe tikọ̀tikọ̀.

**Ta ni Yoo Lọ?**

Nigba ti Labani ati iya rẹ̀ ri itara iranṣẹ yii, ati pe awọn kò le da a duro, wọn wi pe "Awa o pè ọmọdan na, a o si bère li ẹnu rẹ̀." "Nwọn si pè Rebeka, nwọn bi i pe, Iwọ o bá ọkunrin yi lọ? O si wi pe, Emi o lọ."

"Iwọ o lọ bi?" ni ibeere ti Ẹmi Mimọ́ n bèere lọwọ olukuluku ọmọlẹbi Kristi. Eyi ni ọjọ imurasilẹ̀, ọjọ yiyẹ ọkàn wa wò bi Ẹmi ti n pe Iyawo lati tẹle itọni Rẹ̀ ki o si kọ gbogbo ifẹ ayé silẹ (Filippi 3:7, 8), ki oun ba le wọ ibi ikọ̀kọ̀ Ọga-Ogo.

"Iwọ o bá ọkunrin yi lọ?" – bi o tilẹ jẹ pe yoo mu ipinyà pẹlu ide ẹbi ti ifẹ wọn jinlẹ pupọ jù lọ wa? Njẹ iwọ o gba ọna isẹra-ẹni ati ifi-ara-ẹni-rubọ, bi o tilẹ jẹ pe o gbà kikan ara mọ́ agbelebu pẹlu ifẹ inu rẹ̀, ki Kristi le jẹ ohun gbogbo ninu ohun gbogbo? Njẹ ifẹ ọkàn rẹ kọja kikú fun Un nikan, ṣugbọn lati jẹ́ ẹbọ aaye ojoojumọ, ki a ba le kede Ihinrere Rẹ̀ titi de opin ayé? Njẹ o n to iṣura rẹ jọ si Ọrun, ki ọkàn rẹ le maa ronu lori awọn ohun ti ó wà loke ọrun?

Nigba ti Ẹmi ba n fi awọn iṣura Kristi hàn ọ, ati ọrọ̀ Rẹ̀ ninu ogo, iwọ pẹlu Rebeka, yoo wi pe, "Emi o lọ." Bi o tilẹ jẹ pe irin-ajo ti o jin ti o si kún fun ekuru, lori ibakasiẹ le jẹ eyi ti o le mu aarẹ wá, sibẹ̀ nigba ti o bá de ibusọ ti o kẹyin, ni oju ọna naa, ti oju rẹ ba si wo pápá-oko lodikeji ni igba àṣaálẹ́, ti iwọ bá si kòfiri Ọkọ Iyawo, iwọ yoo kigbe pe, "Halleluja!"

## AWỌN IBEERE

1 Ki ni iranṣẹ Abrahamu sọ fun Rebeka ati awọn ẹbi rẹ̀ nipa ọrọ̀ Isaaki?

2 Bawo ni Elieseri, iranṣẹ Abrahamu, ṣe mọ̀ nigba ti o ti ri ọdọmọbinrin naa ẹni ti Ọlọrun ti yàn lati ṣe iyawo Isaaki?

3 Ki ni ohun ti o ṣe, nigba ti o ri i pe oun ti ri ẹni ti a n fẹ gan an?

4 Njẹ a fun Rebeka ni anfaani lati yàn? tabi awọn ẹgbọn rẹ̀ ni wọn pinnu fun un?

5 Awọn ẹbi yii n fẹ ki iranṣẹ naa bá wọn duro diẹ. Ihà wo ni iranṣẹ naa kọ si wọn nipa ero yii?

6 Ki ni eredi wiwá lati ọna jijin lọ bẹẹ lati fẹ aya fun Isaaki?

7 Apẹẹrẹ ta ni Rebeka i ṣe?

8 Apẹẹrẹ ta ni Isaaki i ṣe?

9. Ki ni ohun pataki ti o wà ninu didé wọn ni igba àṣaálẹ?

10 Ki ni ibukun pataki ti a fun Rebeka nigba ti o kuro ni ile?